OWE
Bi a ba ran'ni ni isẹ ẹru, afi t'ọmọ jẹẹ

# Irohin Yoruba

VOL X No 465 MONDAY JUNE 21, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe
Irohin Yoruba

# Oba Oloffa Gba Obafemi Awolowo L'alejo




Aworan oke yi ni ti awọn ogunlọgọ Ọlọpa ti nwọn wa yika ipade ti Ọgbẹni Awolọwọ ba awọn ara Ọffa sẹ.

**OFFA- Ni osan ojo Abameta ti ise ojo kokandilogun osu yi ni Olola Obafemi Awolowo Alakoso Ijoba Iwo-orun Nigeria ati Ogagun Egbe Action Group wa si Offa, Agbegbe Ilorin ni Iha Ariwa (Ieba Ijoba Ile Hausa) pelu awon emewa re ninu Egbe Action Group nwon si wa taara si afin Oloffa Offa, nwon wa fi ola fun eniti ola i se tire.**

Inu Ọlọffa na ati awọn Ijoye rẹ Ṣawo Balogun, Ẹsa, Ọjọmu, Ẹlẹmọṣọ ati Jagun si dun pupọ lati gba wọn pẹlu iyẹsi pupọ.

Lẹhinna na ni nwọn wa lọ si gbangba ojude ile iwe Iyẹru Ọkin lati lọ ba awọn ara ilu ati agbegbe Ọffa sọrọ, awọn ti o wa si ibi ipade na to ẹgbẹdọgbọn enia, ọmọ-Ọba John Oyelade Alaga Awọn Ẹgbẹ Ijẹbu to wa l'Ọffa ni o se Alaga ipade na.

Ọgbẹni Ọbafẹmi Awolọwọ si sọrọ iwuri pupọ nipa awọn isẹ ribiribi ti Ijọba Action Group ti se ati eyiti nwọn si tun nse lọwọlọwọ yi paapa lori ẹkọ ọfẹ ati Ile Iwosan awọn alaisan pẹlu orisirisi isẹ agbẹ ati awọn isẹ ọwọ miran fun anfani awọn ilu abẹ Ijọba Iwọ Orun Nigeria ati idominira Nigeria ni 1956.

O si sọ pe awọn ko ni ki awọn Oyinbo lọ sugbọn awọn ko fẹ pe ki nwọn ma a se ọga l'ori awọn titi lailai ni, nwọn le ma a ba awọn sisẹ bi osisẹ lasan ni. Bi o ti nsọrọ ni awọn na nyombo rẹ pẹlu atewo atẹwọ pipa nitoripe ọrọ rẹ wu wọn lori pupọ.

Awọn Ọlọla E.A. Babalọla (Minister of Works), A.M.A. Akioloye (Minister of Agriculture) ati awọn Ọgbẹni Babs Fani-Kayọde ati Alfred Rewane na sọrọ iwuri lọjọ na pẹlu ti nwọn fi kin Ọlọla Ọbafẹmi lẹhin ki nwọn to tuka. Nigbati nwọn npada bọ si Ibadan, Ọlọla Awolọwọ ya ki Ataọja Oshogbo.



Ọlọta Ọlọffa Offa nki Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ fun ifẹ ti o ni si ilu on lati wa gba awọn enia rẹ ni iyanju lori eto iselu Ẹgbẹ Action Group.

## Awon Ara Eko Ko Faramo Imoran Mbadiwe

**EKO--Ni irole ojo Ojobo ti ise ojo ketadinlogun osu yi ni Awon Egbe Odo Action Group (Action Group Youths' Association) pe ipade gbogbo-gboo si gbangba Ita Balogun l'Eko fun ayewo lori eto itunluse pelu opolopo ile wiwo-lule ti Ijoba ngbero lati se nisisiyi.**

Awọn enia ti o wa si ipade na pẹlu awọn Ijoye Eko to ẹgbaarun enia. gbogbo ohun ti nwọn si da ni imọran ninu ipade na ni gbogbo awọn enia ti o pejọ sibẹ faramọ.

Ọgbẹni R. A. Fani-Kayọde, Alaga awọn Ẹgbẹ Ọdọ na sọ nibẹ pe ohun ti awọn pe ipade yi si ni lati fi enu-sọkan lori ọna ti Ijọba ngbero lati fi tun ilu Eko se, eyiti o le mu t'ori ile t'alejo padanu ohun pupọ.

O ni ti nwọn o ba fi bẹrẹ si wo awọn ile na, eto Ijọba ni lati san owo ti o jẹ fun awọn onile na, ki nwọn ri ibiti awọn ti nwọn ba wo ile wọn yio ma a gbe pe o wa nilẹ, o si tọrun lati gbe ati pe ki awọn alejo mase ri aye gba ilẹ ile ti nwọn ti wo pada fun atunkọ bikọse awọn onilẹ.

O ni kini se ti nwọn ko fi kọ ile si Iru (Ọna-Okun) tabi lọna Ikoyi nibiti awọn Oyinbo gbe nfi ẹsin gba bọlu fun awọn ara Eko ti nwọn ba nlẹ wo ile wọn ti o fi le pa Suru-lere ni ẹbọ Ijọba mu. Ẹ jẹki ati ibẹ yẹ ọrọ na wo daradara.

O si kilọ fun awọn enia pe ki nwọn mase fi eti si ọgbọn ẹtan ti Ọgbẹni K. O. Mbadiwe nlo nitori on ni ẹniti o kọ bẹrẹ si damọran ninu ipade Apapọ Igbimọ-Nla Asofin Nigeria pe ki Eko yapa kuro ninu Ijọba Iwọ-Orun Nigeria ati pe awọn Ẹgbẹ Oselu wọn (N. C. N. C.) ni nwọn ti nfi igbakan sọ ri pe ilu Eko ki ise ilu ẹnikan (eyini ni pe ilu Eko ko l'Oluwa). Fun idi eyi ni a se ni lati kọ gbogbo imọran rẹ lori atunse ti o sọ pe Ijọba nfẹ se fun ilu Eko.

Ọgbẹni H. O. B. Fasinro, Gbakeji Akọwe Ẹgbẹ ọdọ na tun sọrọ, beni Alhaji Muri Animasawun, Iyaafin O Martins, Alhaji Isa Williams ati Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin si se alaye pupọ lati fi kin Ọgbẹni Fani-Kayọde lẹhin.

Nwọn si se ipinnu ninu ipade na pe awọn ko gba eto atunse pẹlu ile wiwo na awọn si tun ki Ọgbẹni K. O. Mbadiwe ti ọwọ ọmọ rẹ b'asọ o, gbogbo awọn enia na si fi ohun sọkan pe awọn fi ara mọ ipinnu ipade na.

## Olota Bo Ninu Ejo Kan

ABẸOKUTA – Ni ọjọ Abameta ti ise ọjọ kọkandinlogun osu yi ni Onidajọ Kotu Kekere Ọgbẹni A. A. Adeshigbin da Timothy Fadina, Ọlọta Ọtta silẹ, o ri pe ko jẹbi ẹjọ ti Ijọba mba a se lori pe, o nse atilẹhin fun awọn Ẹgbẹ Aiyepeju (Ẹgbẹ ti Ijọba ti tuka nisisiyi) pe ki nwọn mase san afikun Owo-ori (Capitation-Tax.)

Onidajọ na sọ pe on ko ni igbagbọ pe Timothy Fadina Ọba Ọlọta jẹbi ẹsẹ ti nwọn mba se ọjọ fun na nitori pe, ẹri awọn ẹlẹri ti nwọn wa lati tako o niwaju on ko dogba rara. O si tun m'enu kan ẹri Erinle, Iyalode Ọtta ti Kotu ti fi igba kan pe pe "ẹri ẹtanu" ni.

Ẹjọ keji ti nwọn se pe Ọba Ọlọta na ji ọgọrun pọnun (£100) si wa ni Kotu Ganran niwaju Adajọ Agba, Adetokunbọ Ademọla, ni ọjọ kẹfa osu ti mbọ ni nwọn a to bẹrẹ ẹjọ na.

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

